Eemọ ni alamọri mumini, dajudaju gbogbo alamọri rẹ oore ni, iyẹn o si si fun ẹnikankan ayaafi mumini

Lati ọdọ Suhayb - ki Ọlọhun yọnu si i - o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe: «Eemọ ni alamọri mumini, dajudaju gbogbo alamọri rẹ oore ni, iyẹn o si si fun ẹnikankan ayaafi mumini, ti idunu ba ṣẹlẹ si i yio dupẹ, ti yio si jẹ oore fun un, ti inira ba si tun ṣẹlẹ si i yio ṣe suuru, ti yio si tun jẹ oore fun un».

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - n ṣe eemọ nipa ọrọ mumini ati awọn iṣesi rẹ ni ti daadaa; ìyẹn ni pe gbogbo ìṣesí rẹ patapata ni oore, ti ìyẹn o si si fun ẹnikankan ayaafi mumini; Ti daadaa ba ṣẹlẹ si i yio dupẹ fun Ọlọhun lori rẹ; ti yio si gba ẹsan pẹlu ọpẹ dida, Ti inira ba si tun ṣẹlẹ si i yio ṣe suuru ti yio si tun retí ẹsan lọdọ Ọlọhun, ti yio si tun gba ẹsan suuru, nitori naa inu ẹsan ni o wa ni gbogbo ìṣesí rẹ.

http://www.sunnah.global/hadeeth/yo/show/3298